IJỌ ÒRÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́-ÌYANU

Olú Ilé-Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà

ÀDÚRÀ SÓRÍ IYẸ̀PẸ̀ (APÁ KÉJE)

1. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, sọ̀kalẹ̀ sórí iyẹ̀pẹ̀ yìí, kí o sì sọ ọ́ di ohun-èlò iwẹ̀nùmọ́ fún agbègbè mi, ní orúkọ Jésù.
2. Jésù Olúwa, jẹ́ kí iyẹ̀pẹ̀ yìí gbé iná Ẹ̀mí Mímọ́ lọ sí gbogbo ibi òkùnkùn tí wọ́n ti n dárúkọ mi fún ibi, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá, nípa iyẹ̀pẹ̀ yìí, jẹ́ kí gbogbo àránsí àjẹ́, tó lòdì sí ayànmọ́ mi padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán an, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ibití iyẹ̀pẹ̀ yìí ṣaṣojú fún, rántí mi fún rere, ní orúkọ Jésù.
5. Bí mo bá ṣe da iyẹ̀pẹ̀ yìí padà, jẹ́ kí gbogbo àmì ibi, ẹ̀rọ ìtọpinpin àti ipa-ẹsẹ̀ sátánì l'ágbègbè mi parẹ́ pátápátá, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá, jẹ́ kí iyẹ̀pẹ̀ yìí fọ agbègbè tó mbẹ̀ láyiká mi mọ́, ní orúkọ Jésù.
7. Nípa iyẹ̀pẹ̀ yìí, mo sọ gbogbo ògèdè àti gbólóhùn sátánì tí wọ́n sọ l'ágbègbè mi di aláìlágbára, ní orúkọ Jésù.
8. Pẹ̀lú iyẹ̀pẹ̀ yìí, Bàbá, jẹ́ kí gbogbo ohùn àjèjì, ìfarahàn àjèjì àti ìmísí agbègbè l'ágbègbè mi panumọ́, kí ó sì kúrò, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ibùkún tí ilẹ̀ ti gbé mìn l'ágbègbè mi gba ìtúsílẹ̀ fún mi, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, bí mo bá ṣe da iyẹ̀pẹ̀ yìí padà, jẹ́ kí ó rin ìrìn-àjò dé ọ̀dọ̀ gbogbo ìránṣẹ́ òkùnkùn tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayé mi, kí ó sì pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, jẹ́ kí iyẹ̀pẹ̀ yìí gbé ìlọ́po méji agbára ogun-jíjà lọ sí àgọ́ àwọn ọ̀tá mi, kí ó sì fọ agbègbè mì mọ́, ní orúkọ Jésù.
12. Mo pàṣẹ wí pé gbogbo ibití ẹsẹ̀ mi bá tẹ̀ yóò fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.

13. Agbárakágbára tó n pògèdè sínú iyẹ̀pẹ̀ lòdì sí mì, ṣubú nípa idà rẹ, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ifìmọ̀sọkan ibi láàrín ayànmọ́ mi àti agbègbè mi, gba ìfagilé nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.